# EKO AKETE.

IWE IROHIN OSOSE.

VOL: I. No. 8. SATURDAY, SEPTEMBER 2 1922. THREEPENCE

*Editor:*—ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Odun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Osu mefa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Osu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranse si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

### KINLA! KINLA!! KINLA!!!

A gbọ agbọsọ kan pe diẹ ninu awọn enia wa kọ iwe abami kan ti nwọn fi ọwọ si, ṣọwọ si Ijọba lati sọpe nwọn ko ni ọwọ ninu Ọrọ Ẹbẹ fun Eleko mọ. KA-ṢI-MA-WO O.

### A KI IṢ' ỌRE ERO KA YỌ.

Ojiṣe-Ọlọrun kan, Iyekan Casely Hayford, Ọlọla ara Sekondi, ti a npe ni Mark Hayford, Igi-Iwe Ijinlẹ ninu Isin Ọlọrun, (D.D.) ya bara kẹsi wa ni ijọ 22 oṣu to kọja: Igi-Iwe na ba ọkọ Elmina de, o si ba a lọ si Calabar: a ni ireti pe yio tun pada wa sibi lati wa tu owo jọ fun iranlọwọ Ile-iwe giga kan to ti nkọ lati ọdun kẹrin sẹhin, (1918): to si ṣeṣẹ pari: Ile-iwe giga na wa ni Ita Hansen (Hansen Road) ni Accra, awa papa lọ bẹ ibẹ wo ni ọdun keji ọhun (1920,) nigbati a fi lọ si Ipade Gbogbo Enia Dudu Ekinni ti a kọ ṣe ni ilu Accra, ninu oṣu *March* ọdun na. Igi-iwe yi nfẹ owo titujọ fun sisan fun awọn olukọ rẹ ni Ile-iwe na.

### IBADAN ỌMỌ AJORO SUN.

Iṣẹ gbe wa lọ si Ibadan ni ijọ 17 oṣu tokọja, ninu eyiti a wa aye lati lọ ki Ojiṣẹ-Ọlọrun Charles Doherty ni Kudẹti, ati awọn ojulumọ diẹ: Alufa na si gba wa towọ-tesẹ lai jẹ pe o ti mọ bibọ wa tẹlẹ. A ba a yọ ti Alejo ọkunrin kan ti iyawo rẹ ṣe e ni lọlọyi. A ṣe Ọkunrin!!!

## IYALODE ANIWURA.

Awọn Ẹgbẹ Ọmọge ti Ayaba wa, Lady Clifford nṣe Iyalode wọn, ṣere idaraya kan lana ni Ile-Iranti Afari-ogun: (*Glover Memorial Hall*) o gba fun wọn pupọ.

---

## ENITI A NPERI KO TO NKAN.

Ọgbẹni F. W. Morais, Igi-Iwe to "fọgi" ọrọ sisọ ni Apejọ kan ta ṣe ni Ile-iwe giga ti Eko laipẹ yi, ti ile fi kun akunya ke si ni ni ibi-iṣẹ wa ni ọjọ diẹ sẹhin, o si ba ni sọrọ pupọ nipati ilọsiwaju ilẹ wa ninu Ẹkọ Giga gẹgẹ bi enia dudu: bi o ri jagun na, o ko ni mọ pe Atari-Ajanaku papa ninu iwe ni. O wọ aṣọ bi ẹnikan lasan. Igi-iwe yi npete lati sọ Asọ ye miran laipẹ (*Lecture*)

---

## ỌMỌ ADE GORI ADE.

*Pastor* A Adedeji Iṣọla ṣe Akanṣe Iwasu kan lori Alamori "Ita ati Ije" oku sisin gẹgẹbi Onigbagbọ, ni *Church Brotherhood* Ilupesi, ni ijọ-ọsẹ to kọja: Ṣeranwo ni Iwasu na, o kun fun ẹkọ ati ironu-ijinlẹ lọpọlọpọ. A tanma lati tẹ Iwasu na sinu iwe yi.

---

## KINNIUN ONIBUDO LỌ S'AJO.

Ọgbẹni Herbert Macaulay C.E. onitan ye. (*our historian*) dalẹ lọ si ẹnu iṣẹ lapa Ibu-Ode ni ọsẹ diẹ to kọja.

---

## "OṢE! ARAKUNRIN MI!"

A ba awọn ẹbi Ọgbẹni Oni-gbanjo Charles Cameron Cole kẹdun iku oni-[b]anjo na, to ṣẹlẹ ni *Monday* ọsẹ yi. Ọrun !!!

## IPO AWỌN ỌMỌDE.

LETTER No. 6.

Ekọ
2nd Sept., 1922.

Ẹnyin Ọrẹ mi Ọwọn,

Gẹgẹ bi mo ti sọ ninu iwe mi kinni, Letter No. 1, pe ẹnikẹni ti o ba nfẹ ba mi sọrọ ki o kọwe si *Editor* Eko Akete ki o si fi orukọ Eleti Ọfẹ si i, ki o fi ranṣẹ si 24 Williams Street; inu mi dun pupọ lati sọ pe, mo ri iwe kan gba lati ọwọ ọkan ninu nyin ti ọrukọ rọ njẹ Yakin S. Oriọla. O dupẹ lọwọ mi pupọ nipa ọrọ iyanju ti mo mba nyin sọ lọsọsẹ, o si gbadura fun Eleti Ọfẹ pe ki Ọlọrun ki o fun u ni ara lile ati iranlọwọ lati ma ba ọrọ iyanju yi lọ.

Ẹnyin ọrẹ mi kekere, inu mi dun pupọ nigbati mo ri iwe yi gba, o fihan mi gbangba pe a ri ninu nyin ti o nka iwe yi; bi ko ba si idiwọ kọkan, mo ti pinnu lọkan mi lati ma ba ọrọ iyanju mi lọ lọsọsẹ. Inu mi yio si dun bi mo ba nri iwe olukuluku nyin gba, ki ẹ si ma bere ohun ti ko ba ye nyin lọwọ mi.

Ọrọ ti mo fẹ ba nyin sọrọ nipa rẹ lọsẹ yi ni "Aigbọran," eyiti itumọ rẹ ni ede oyinbo njẹ "*Disobedience*" Ojẹ aṣa ẹnyin ọmọde lati ma ṣe aigbọran si awọn obi nyin, ati awọn olukọ nyin, iwa na ko dara, o si buru pẹlu. Iwa buburu ima ba iwa rere jẹ.

Kini imu aigbọran wa? Iwa Ipata: iwa aibikita, iwa ọmọ-ita, ati iwa aini ibẹru enia lọkan ati iwa igberaga, iwa oṣonu ati iwa agidi, iwonyi ni o ma nmu aigbọran wa.

Kini ere aigbọran? Gbogbo nyin ni o mọ eyi, diẹ ninu wọn ni iwọnyi:—Wahala, idamu, iyọnu ati iya-jijẹ, eyiti a le fi orukọ kan ṣoṣo fun, *Punishment* li ede oyinbo.

Iwa wo ni iwa aigbọran? Bi olukọ nyin ba ni ki ẹ ma sọrọ ni ile-ẹkọ, ti a si ri ẹnikan ki o ma sọrọ, aigbọran ni eyi; bi olukọ ba ni ki ẹ ma ji iṣiro ti ara nyin wo ti a ba ri

ẹnikan ninu nyin ti o nji ti ẹnikeji rẹ wo, aigbọran ni eyi; bi awọn obi nyin ba kilọ fun nyin pe ki ẹ ma ṣe nkankan ti ẹ ba si da aṣẹ wọn kọja, ti ẹ si ṣe ohun ti nwọn ni ki ẹ ma ṣe, aigbọran ni eyi pelu. Gbogbo ohun ti o ba lodi si aṣẹ tabi si ifẹ awọn olukọ nyin ati awọn obi nyin jẹ si aigbọran. Iya-jijẹ ni ere aigbọran, bi o ti wa fun ọmọde, bẹ na ni o wa fun agbalagba, nitori bi ọmọde ti njere ẹṣẹ rẹ na ni agbalagba pẹlu. Gbogbo nyin ni o mọ itan awọn ọmọ Eli ti nwọn jẹ alaigbọran, ati bi Ọlọrun si ti jẹ wọn ni iya ẹṣẹ wọn. Nitorina, mo bẹ gbogbo nyin ki ẹ fi kọra lati ma gbọ ohunkohun ti awọn olukọ nyin ati awọn obi nyin ba sọ fun nyin, nitori bi ọsan ti ntẹle oru, bẹni ere-ẹṣẹ ima tẹle aigbọran; ati nitori ki ẹ ma ṣe jẹ ọmọ alaigbọran ni o mu mi lati gba nyin ni iyanju lọsẹ yi lori aigbọran.

Ẹjẹ ki nfun nyin ni itan kekere kan lati fi han nyin pe aigbọran ima mu adanu wa gẹgẹ bi ere rẹ: awọn ọmọde kunrin meji kan wa, nwọn jẹ ọmọ enia nla ti baba wọn wa ni ipo ọla, awọn mejeji jẹ ọmọ alaigbọran, nwọn kilọ fun wọn titi, nwọn ko gbọ, nigbati o di ọjọ kan ti nwọn ma jere ẹṣẹ wọn lọjọ kanna ni Ọlọrun jẹ awọn ọmọde wọnyi niya. Aigbọran ko dara, o ma ntọka si iparun nikẹhin. Itiju ati ẹgan ni awọn ọmọ alaigbọran ima mu wa fun awọn obi wọn. Nwọn igbati ẹnikẹni ninu nyin ko fẹ jẹ ọmọ ti o ma mu itiju wa fun obi rẹ, nitorina ẹ ma kọ lati ma gbọran si awọn obi nyin lẹnu.

Ọrọ ti mo ma fi ba nyin sọrọ lọsẹ ti o mbọ bi Ọlọrun ba fi ẹmi ati ara lilẹ ta mi lọrẹ ni igbọran eyiti oyinbo npe ni *Obedience*.

Ẹ ku ojo yi pẹlu otutu rẹ. Mo ro pe gbogbo nyin li o mọ bi nwọn ti npe ojo ti o nrọ lọsẹ yi; eyi ni awọn baba wa ma npe ni Ojo Arọ-kuro, eyiti awọn eyin o npe ni "*Latter Rains*."

Emi ni ọrẹ nyin nitotọ
ELETI ỌFẸ.

---

Ọgbẹni mi ọwọn *Editor*.
Eko Akete.

Inu mi yio dun lati ripe a o gba mi laye lati fi ọran wọnyi han agbagba ati awọn ẹlẹgbẹ mi ni ilu.

Gẹgẹ bi o ti jẹ pe nko le ri ki nma sọ ati pe bi ati mọ pe iyẹ ti ko ba sunwọn lara ẹiyẹ oye ki a fa kuro. Ni ọjọ Friday oṣu August yi mjọ kọkanla mo ṣe akiyesi ọrọ ṣoki kan ninu iwe irohin *African Messenger* nipa ọrọ alufaṣa ati ọrọ eri ti o sọ si ohun ribiribi ti iwe ẹbẹ ti gbogbo ilu Eko yi nfẹ fi bẹ Gomina Clifford nipa ọrọ Eṣugbayi Eleko wa ati ile Dosunmu. Ohun pataki ti o ya mi lẹnu ninu isọkusọ ti iwe irohin yi sọ ni pe "Ilu ha kọ ni awọn ti ngbero ti wa lati bi ọdun mẹta sẹhin ati pe bi wọn rope arabara ti wọn te iwe ẹbẹ na ni yio mu ki Gomina gba ẹbẹ wọn" nisinyi ẹjẹ ki a wotọrọ na ni ede ti ilu wa ni Eko yi, ti ki si ṣe ede ilu kekere kan to wa labẹ ijọba Eko y...

Ede ti wa nipe bi ọmọ ba ṣẹ baba rẹ iṣẹ... lati lọ torọ aforiji, ti baba na ko ba si ni ite... ọmọ na ni lati pe awọn agbagba jọ ki wọn tu... on bẹbẹ, nipa bayi bio tiwu ki baba na binu to... ro ti awọn agbagba ilu na yio ṣe idariji ... ikilọ. Nisisinyi a ripe *African Messenger* jẹ ọk... ninu enia ti a le ma pe ni "ko ṣ'eku ko ṣ'eiyẹ" ... eria. Bi mo ba ṣe iranti sẹhin a o ri dajudaju pe alabojuto iwe irohin *African Messenger* yi jẹ ọkan ninu awọn to nla oran ye ijọba yi nigba... gbolohun asọ yi ṣẹlẹ larin Esugbayi Eleko ... ijọba. Nisinyi a le ripe *African Messenger* jẹ ... irohin ti a le pe ni "ko ṣ'eku ko ṣ'eiyẹ" ajawo ... ṣugbọn ohun kan ni mo lẹ ki alabojuto *African Messenger* mọ pe "ko si ohunkohun ti a le s... fun Ifa ti ko ni huwa Ekurọ" ngo ṣe iru esi bayi ṣọwọ ni ede Gẹsi fun awọn tiko mọ ede yoruba ka mo dupẹ fun iba aye ṣoki yi.

MAKANJU.

---

37 Ẹlẹgbata Street,
Lagos, N. 21, 8.

Editor "Eko Akete"
Si Ọgbẹni Eleti ọfẹ ọrẹ ọmode.

Bismi lahi rahmani rahimmi,

Inu mi dun lati fi ọpọlọpọ ọpẹ fun o fun iranti... igba ni niyanju ti o ṣe fun awọn ọmo ile Ẹkọ. E... gigun ati ara lile fun ọ Oluwa ki o tun bọ ran ọ lọw... ki ole ma lọsiwaju ninu gbigba ni niyanju rẹ s... ọmọ ile Ẹkọ, ninu *Letter Nos.* 2. ati 3. modupẹ lọwọ Oluwa fun ọpọlọpọ ọgbọn ti o fun wa ninu rẹ ati iyanju: emi ko ni ba ọrọ mi lọ ni gigun ju ki ndupẹ ma si ma reti ọrọ iyebiye rẹ ninu "Eko Akete." Oluwa ki o si ṣi awa ọmọde leti lati ma gbo ọrọ iyanju ti awọn agba yio ma ba wa sọ. *Amin.*

Alihamdulilai

Emi ni tirẹ nitotọ,

YAKIN S. ORIỌLA
*Muslim School Boy*

## EKO AKETE.

EKO SATURDAY, SEPTEMBER, 2, 1922.


### EKO GB' OLE, O GB' ỌLẸ.

Ẹnu ko le ṣe ko ma ya ni fun diẹ ninu awọn ara ilu ti a gbọ pe nwọn salọ si Ebute-Mẹta, Idi-oro ati ibomiran ninu ọsẹ to kọja, nitoripe awọn kan sọ pe Eko yi io parẹ ni *Saturday* ọsẹ to lọ.

Irufẹ dida enia niji bayi ti wa ki iṣe oni: ...nti pe bẹ ni awọn kan fi ẹnu wọn sọ ni ...m kẹtadilọgbọn sẹhin (1895) pe Eko ... di ilu igbagbe ninu oṣu *July* ọdun na: ... mọ awọn enia ti irufẹ asọtẹlẹ-eke yi ...a lāmu, titi akoko na fi kọja lọ ti pẹkẹ ko ...i. Ti a ba wadi isọkusọ yi, a ko ni ṣai ri pe awọn olõraye enia ti nwọn nwa onjẹ lati fi ...nu tu jẹ.—Ode sa le diẹ nisisiyi—ni nwọn ...fi oku-ọrọ bayi ṣe Iwasu ni opopo-ode: ...tilẹ ri ẹnikan ti irufẹ ọrọ yi da lamu to sọ ...un wa pe, bi-iṣẹju, on nlọ wa ibi kan fi ori pamọ si, nitoripe ọrọ na kuro ni awada: bẹ ...ẹni yi jẹ oniwasu Kristi ti o mọ dajudaju pe Jesu Olukọ ati Ọga rẹ sọ ni iwe Bibeli pe Kosi ẹniti o mọ ọjọ na (eyini ni ọjọ ikẹhin aiye,) ki i ṣe awọn Angẹli, bikoṣe Baba ...ikalarẹ nikan. Kosi nkan ti ebi ko ni mu awọn miran ninu awọn oniwasu opopo-ode lati sọ, ki awọn enia le fi bi tọrọ (3d.) tabi sisi (6d.) kan ju wọn lori, nigbati nwọn ba sọ pe nwọn ngbadura fun wọn: ninu awọn oniwasu wọnyi ni "nhọrọjọ-bi-ologbo-Idumọta," o miran a tilẹ ma ṣepe, nwọn a tutọ soke nwọn a fi oju gba a, bẹni "ebi-ogaja-fọwọ-mẹkẹ lo nsọ wọn di Alapa-...aṣiṣẹ bayi, nwọn di "Ọlẹ-ba a ti, o ko 'le keu". Ogo ni ẹkọ-kẹkọ ngbilẹ ti o fi jẹ pe enia ko tun gbọdọ fi ẹdọ-le ri ororo mọ, a fi bi awọn oniwasu-alayọnusọ wọnyi ba nsọ ohun ti oju wọn ko to:

Yio jẹ ohun to dara ti awọn ara ilu ko ba nani ọrọ-were bayi, Eko sa gb' ole, o gb' 'ọlẹ, o gba ikan yoku !!! Kaka ki awọn irufẹ enia nwọnyi lọ wa iṣẹ pataki ṣe, agbẹdọ, a fi bi nwọn nwa ẹniti nwọn ma fi ti wọn kọ lọrun nipa ẹkọ afọri wọn. "Ma fi ti ẹ kọ mi lọrun" lo da fun ẹkan on owu.

O di igbati ọwọ ba tẹ diẹ ninu aw... oniwasu alusi wọnyi, ti Ofin ba kọ wọn lọgb... ki nwọn to mọ pe "Idi la nso Ifa mọ, Ọpẹlẹ ki ngb'ọrun."

---

### ỌRỌ EṢUGBAYI ELEKO PẸLU IJỌBA.

Ọrọ yi jẹ ohun pataki ti o nfẹ ero-ijinlẹ ati ọpọlọpọ ọgbọn. Bi a ba si ni ki a sọ otitọ fun ara wa gẹgẹ bi ara ilu, ọrọ na ko ṣoro lati sọ. Eleko fun ara-rẹ ko ni ẹbi pupọ ninu ọrọ Ọpa Akitoye ni Ilu Oyinbo, Ọgbẹni Macaulay ti o si nja fun Eleko ni Ilu Oyinbo nipa peki nwọn fi owo kun owo rẹ ati pe Eleko ni o yẹ ki o jẹ olori awọn Ijoye Ilu-Oke ti o si nja fun u lọrọ ẹnu ati ninu iwe ko ni ẹbi, Ijọba ti o si ni awọn ko mọ pe nkan bayi ni Ọgbẹni Macaulay nlọ sọ ni ilu Oyinbo lai jẹ imọ tiwọn tẹlẹ gẹgẹ bi Ijọba, nwọn ko jẹbi bi nwọn ba binu si Eleko fun aisọ eyi fun wọn ṣiwaju ki Oloye Oluwa ati Ọgbẹni Macaulay to lọ kuro l' Eko ṣugbọn tani o ha ni ẹbi ọrọ banta-banta yi? Awa ara ilu papa ni a lẹbi. Nigbati ẹnu wa ko ṣọkan, ti ko si irẹpọ larin wa gẹgẹ bi orilẹ-ede kini ire ti a nwa fun Eleko ti ṣe le tẹ wa lọwọ. Nigbati a ko ni fi ipo olori fun olori, ti o jẹ pe gbogbo wa ni o nfẹ ṣe ti inu wa, ki aiye ri mi, ti a ko pa imọ wa pọ, kini ohun rere ti a nwa ti ṣe le tẹ wa lọwọ fun Eleko ati Ile Dosunmu, gbogbo wa ni a ti ṣina kuro lọna otitọ a fi ohun ti a ba ṣe silẹ, a si nṣe ohun ti a ki ba ma ṣe.

Nisisiyi Ijọba sọ pe awọn ko ka Eleko si mọ, awọn nfẹ ẹlomiran ni Ile Dosunmu eyi gba ero, bi a ba wo ipo Eleko si Ijọba lati ẹnu ọdun mẹta wa, ṣugbọn bi a ba ni ki nwọn mu ẹlomiran wa, bayi na ni wahala yio wa fun u. Nigbati Ijọba ba nfẹ nkan, boya awọn Ilu ko fẹ ti ewo ni o ma ṣe, ko ni fẹ ṣẹ Ijọba bẹni ko si ni fẹ ṣẹ awọn Ilu ti o fi sibẹ, nihin ni ọrọ yi nipọn si. Eyi ni o nyọ Eleko lẹnu. O ṣoro ki ẹnikẹni ti o ba bọ sile ko to le ṣe oju ilu ki o si tun ṣe oju Ijọba lai jẹ pe yio ṣẹ ẹnikan ninu

awọn mẹjeji otitọ ni ọrọ Bibeli ti o ni "Iwọ ko le sin Oluwa meji."

Bayi na kọ ni a o ma da ara wa lamu? Ọrọ yi gba ero-ijinlẹ pupọ. Nitori eyi ni a ṣe sọ pe o tọ ki a bẹ Ijọba ki o gba ọrọ Eleko yẹ wo. Ko tọ ki nwọn binnu si Eleko rekọja-ala nitori ọrọ yi, Ilu ni o yẹ ki a kilọ fun pe ki nwọn fi imọ wọn si oju kan. Ija ti o fi idimulẹ larin awọn Imale, ti nwọn fi nmu ara wọn lọ sun ni Ile-Ẹjọ nigbagbogbo o nfi airoju fun ọrọ Ijọba pẹlu Eleko, nitori ẹsun igbagbogbo yi fi han gbangba pe kosi irẹpọ larin wọn, bẹni awọn ni ẹni pataki ti o nṣe ilu, a ko ro pe a le fi ija ati ipe-ara eni lẹjọ, tun ilu ṣe. Mo sọ ni ọsẹ ti o kọja pe ki a wi fun Eleko pe ki o tun mura lati tun ẹru rẹ di, eyiti o ti bẹrẹ si wọ lati ẹnu ọdun kẹta.

Kini ohun ti o yẹ ki ilu ṣe lati mu gbogbo wahala yi kuro lọna Ipo tiwa ni lati sọ otitọ, eyiti o ma nkoro leti awọn ẹlomiran. Niwọn igbati ija Imale ko ba pari si rere, idarudapọ ko ni ye ma wa larin wa, nitori ọrọ Imale ni gbongbo ọrọ ilu. Bi awọn ti npe Lemọmu lẹjọ ba le fi ẹjọ pipe silẹ, ti nwọn ko si jẹ ki ẹnikẹni ki o ma sun wọn na owo ni aisinmi mọ, ti irẹpọ ba otitọ wa larin wọn, ilu yio toro bi omi amu. Ti ero Eleko ati Lemọmu pẹlu gbogbo awọn Imale lori awọn ẹniti o jẹ Lemọmu le ba papọ mọ ti Ọgbẹni Carr Alabojuto Ilu ti ko si ẹnikan ta ẹnikeji rẹ laya nipa ọrọ-sisọ tabi nipa iwe kikọ, alafia yio wa larin Ilu, ṣugbọn bi o ba ṣe pe a o ma mu ara ẹni lọ si Ile-Ẹjọ nigbagbogbo ni a joko si a ko le ri alafia ti a nwa larin wa. Bi a ba fẹ ki ọrọ Eleko pelu Ijọba ki o loju, ki a bẹ awọn Imale ki wọn pari ija wọn pẹlu Lemọmu na, nigbana ọna yio la.

ELETI ỌFẸ.

---

## ẸBUN FUN AWỌN ỌMỌDE

Mo pese ṣile kan (1/-) fun awọn ọmọde meji, sisi-sisi fun ẹnikọkan ti o ba le sọ fun mi ni asọye nipa Iri (*Dew.*)

1. Mo fẹ ki ẹ kọ ọ li ede Yoruba ti o dara.
2. Ẹniti Yoruba-kikọ rẹ ko ba dara ko ni gba ẹbun.
3. Nko fẹ ki ẹnikẹni ki o bere iranlọwọ ẹlomiran.
4. Awọn ọmọde ti o nlọ si Ile-Ẹkọ ni mo pese ẹbun yi fun.
5. A o tẹ orukọ awọn ọmọde meji ti o ba ṣe dada sinu iwe Irohin yi.
6. Gbogbo iwe-esi ni lati ba wa lọwọ titi di *Saturday* ọjọ kẹsan oṣu September (Sept. 9).
7. Mu Iwe-esi rẹ wa si 24 Williams Street, ki o si kọ gbogbo orukọ rẹ si i tan.

ELETI-ỌFẸ.

*Ọrẹ awọn Ọmọde.*

---

**Report of a Lecture on "Education" delivered by Professor F. W. M. Morais, M.A., Ph.D. (Harvard) of Cuttington Colleges, Cape Palmas on the 15th August, 1922, at Eko High School Hall, Lagos.**

---

The Lecturer was called upon to deliver his Lecture at 5.30 p.m. prompt by Rev. W. B. Euba, the President of "The Private Schools Head-masters' Association under whose auspices the Lecture was delivered. Prior to this, Rev. Euba led the audience to the throne of Grace with an appropriate prayer which was cleverly linked up with the Lord's prayer. He introduced the Lecturer in words suitable for the occasion; he said that the Professor had extraordinary things to say, he had a Mission to perform and a Message to give.

In truth, the statement of Rev. Euba was corroborated by the Lecturer. He did say extra-ordinary things, for his exordium consisted of French and Latin quotations; high flowing phrases and technical terms pervaded the whole of his speech.

After the Lecturer had given the definition of "Education" in flowing terms, and enumerated its numerous advantages, he initiated the audience into the mystery of Philosophy, Physiology, Pyscometry, Magnetism, Mesmerism and all the other "isms;" after which he digressed to the other part of his address, namely, his Mission.

In the course of the second part of the Lecturer's address, he said that he was voicing the sentiments of "The American Church," *i.e.* The Prostestant Episcopal Church in America to give university education to the Negroes of West Africa and that this Church is prepared to erect Colleges all along the West Coast of Africa, to wit, Sierra Leone, the Gold Coast, and Nigeria, and that expenses will be met by the Church, but what is required of the people is co-operation. These Colleges shall affiliate with the University of New York.

Rev. J. C. Cole, Rev. E. T. Johnson, Dr. A. Savage and Mr. T. H. Jackson, Editor of Lagos Weekly Record, addressed the audience respectively. These addresses of the respectable gentlemen made the situation clearer than it at first appeared. Among other things, Dr Savage said and convinced the Lecturer that if he expected any financial support from the people he will be disappointed.

The high sounding bell of the "Holy Cross Cathedral" interfered with the decorum of the meeting, and Dr. Savage who was addressing the audience at the moment said that they should not mind the bell which was performing its own work.

Comparatively speaking the meeting was largely attended, but unfortunately the benches were not properly arranged previously as to conveniently sit the audience.

As to the personality of the Lecturer-Professor Morais, little is known beyond the fact that when learning is taken into consideration he is unquestionably a credit to the race.

After the audience had expressed their gratefulness to the Lecturer for his splendid address, the meeting was brought to a close at 6.30 p.m. with Benediction.

ELETI-ỌFẸ.

## LAWYER SHYNGLE NI ILU ONDO.

LAWYER SHYNGLE de ode Ondo ni Alamisi *Thursday 17th August* ijọ kẹtadilogun ọṣu *August*. Ṣaju ki o to wa ni ati ran Oloye GINITU. Ọkan ninu awọn Ijoye Ondo lati lọ si Eko, si ọdọ awọn ọmọ wa ti o wa nibẹ nipa ẹjọ ti Ajẹlẹ ti o wa nibẹ da fun wa ti ko wọ fun wa; ẹjọ yi jẹ ẹjọ ilẹ larin awa ati Ikalẹ. A ti fi ọrọ yi han Ajẹlẹ Agba ni Akurẹ, o si sọ wipe, bi a ko ba gba ẹjọ ti Ajẹlẹ da fun wa ki a ma mu ẹjọ lọ si Eko *Appeal Court*

Nigbati GINITU de si Eko, on pẹlu awọn ọmọ Ondo ti o jẹ pataki ro ọrọ na titi, nwọn ni ko si ṣiṣe ko saiṣe, o ya na niyẹn, kini ki a ti gbọ, Ikalẹ kẹ, iya mọnamọna o d' ẹjọ nla ni yẹn, ko si 'si ẹniti o to ẹjọ yi ko loju bikoṣe Lọya Agba, "Logun L'Eko." Laifagun lọ titi o di ọdọ Kiniun ni gbangan Idajọ *Lion of the Bar* nwọn sọrọ lọ sọrọ bọ, Adehun pade, a si fi ọjọ si ti *ori ọrọ* yi o tẹ Lọya lọwọ. Lọya papa si wa ṣe ileri pe iru ẹjọ bantabanta ti nwọn mu wa fun on yi, o yẹ ki on lọ fi oju kan awọn Agbagba lati wadi itan ati bi ẹjọ ti ri ki a ma da lọ wẹrẹ. irohin kan nipe Olori Agbẹjọro ti *Nigeria* (*Leader of the Bar*) nbọ wa fi oju kan ilẹ Airọ, gbogbo ilu bẹrẹsi mura fun alejo nla yi. A gbọ pe nwọn dide ni *Tuesday* ijọ kẹdogun oṣu *August*, on ati ọmọ Ọba *Vincent* ẹniti iṣe Baba isalẹ Ẹgbẹ Ondo ti o 'nbẹ l' Eko, nwọn wọ moto de bi *mile* mẹjọ si Ondo ni owurọ *Thursday*. Ki a to de ibiti ọna moto pẹkun si, irohin ti kan de Ondo pe nwọn nbọ l' ọna, a si ti ran ogunlọgọ enia lati mu Ibapo ati Ẹṣiu, lati lọ pade rẹ pẹlu ilu ati ijo, ọjọ l' ọjọ na jẹ fun wa, ọjọ ti a kole gbagbe lailai fun irandiran.

Alejo wa yi wọ 'le ni iwọn agogo mẹwa arọ a si mu lọ si pẹtẹsi LADAPỌ AKINKUGBE ni odo Dibo, bi o si ti gun oke ile ti a fi wọ si, ihin kan Ọba pe alejo ilu de; Ọba si ran awọn Ijoye wọnyi lati lọ ki, GINITU, LAMUFE, ati BAPAIYE, nigbati nwọn de ọdọ rẹ, nwọn ki i lọpọlọpọ, on na si ki wọn, o si ranṣẹ pada si Ọba pe o rẹ on pupọ, on si fẹ simi, bi o ba di ijọ keji ni agogo mẹwa on yio wa f' oju kan Ọba. Titi ilẹ fi ṣu ni ero nwọ lọdọ rẹ lati lọ ki i.

Ọpọlọpọ wa ti o ti ngburo oruko rẹ fun iṣẹ ti o nṣe fun ire ilu Eko, fun ọmode ati Agba ni ireti ati ri ẹnikan ti o ṣe gbọngbọran bi Omiran, afi nigbati o de, ti o jẹ ẹniti o kuru, o sanra, o si pupa diẹ, o dara pupọ, awọ rẹ si tutu; ọrọ ẹnu rẹ dun, o si dun wo bi o ba nsọrọ, ohun rẹ ko yatọ si ti Oyinbo rara.

Dide rẹ bọ si akoko "Ọdunba," ẹsẹ awọn Ijoye gbogbo fẹrẹ pe tan, awọn Saraki Ilu gbogbo ti pada bọ lati oko iṣẹ wọn, ati lati eti odo nibi ti wọn gbe nṣowo, nitori "Ọdunba" jẹ Ọdun nla fun Ondo, o dabi ti Keresimesi ti ri fun Oyinbo. Nijọ *Friday* eyiti iṣe ijọ keji ti o de awọn Ijoye ti pe si ile Ọba ati ọpọlọpọ enia, nigbati o to iwọn agogo mẹsan Lọya dide ni ile rẹ pẹlu kẹkẹ *Rickshaw*, LADAPO ẹniti nṣe Bale rẹ g' ẹṣin, ọpọlọpọ ọdọ-mọkunrin si gba tẹle wọn lori Bicycle ati l'ẹsẹ, bi nwọn ti nlọ o ya lọ si ile ẹkọ giga ti ilu *Boys Public High School* eyiti Alufa ADEYEMI ẹniti o ja fafa ninu ẹkọ nṣe Olori rẹ, O ki Ọga ile ẹkọ na, a si fi awon ti o nṣiṣẹ nibẹ han, lẹhin eyi o rin kakiri, o si wo iṣẹ ti nwọn nṣe, o wá kuro nibẹ o ta mọ kẹkẹ rẹ, o di ile Ọba, nigbati a mu wọ Afin, Ọba ti gunwa patapata gba, o wọ ile O si ki Ọba tọwọ-tọwọ (ko gbọwọ lọwọ rẹ, nitori Ọba Oṣemawe ki gbọwọ lọwọ enia) a si mu lọ si ibujoko rẹ; lẹhin igbati nwon sọrọ lori ohun ti o gbe wa si Ondo tan o ba ilu sọrọ iyanilori pupọ, o ni o ya on lẹnu pupọ lati ri ile nlanla bayi ni Ondo, ati awọn Opopo nlanla wọnyi ti o dara ti o si mọ finnifinni, o ni eyi fihan pe awọn Ondo jẹ alap[illegible] ati oṣisẹ enia, o si da on l' oju pe bi *Railway* t[illegible] ọna *Motor* ba la iru rẹ ja bi awọn ilu miran, l[illegible] aniani ilu ti yio le farawe Ondo yio mura; O[illegible] kan ile iwe giga ti ilu O ni inu on si dun pupọ

awọn Alaṣẹ ilu yọda Igba Pọun lọdọdun fun ile iwe na, o ni eyi dara pupọ, nitori ẹkọ ni o ngbe orilẹ-ede ga o si ni ibukun pupọ. Ọba ṣe l' alejo daradara, Ọti nlanla la ṣi nibẹ, *Champagne*, ati *Cigar* olorun didun; gẹgẹ bi ọjọ na ti jẹ ọjọ aisun idanna ti Odunba *Watch Night* o kuro nibẹ niwọn agogo mẹta o si pada lọ si ile pẹlu ọpọlọpọ enia.

Ni ọjọ *Saturday* awọn ọmọ ile ẹkọ Giga pe e lati wa woran *Football*, ere yi bẹrẹ niwọn agogo mẹrin lẹhin ti ere yi pari, o sọrọ pupọ, o gba awọn ọmọ na niyanju o si ṣe ileri pe on o ra *Bat* ati *Ball Cricket Materials* ti yio na on to Pọun mẹwa on a si ma fi Pọun marun ṣọwọ lọdọdun gẹgẹ bi ẹbun fun ẹniti o ba ṣe dara julọ ni ede Oyinbo ati *Latin*.

Ni alẹ *Saturday* Ọga ile ẹkọ giga pe e sibi apejẹ Oloye LOMOFE wa nibẹ pẹlu. Iyawo ADEYEMI si se adidun Oyinbo l' oniruru, Ọti Oyinbo nṣan agbara l'alẹ ọjọ na. Ki a to kuro nibi onjẹ yi, ilẹ ṣu pupọ.

Ni ọjọ Ọsẹ ko lọ si ibi kankan, o sinmi si ile ṣugbọn awọn enia patakipataki ko yẹ wọ lọdọ rẹ.

Ni arọ *Monday* o lọ si Oke Aluko lati lọ ki Alufa PHILLIP ati aya rẹ ẹniti iṣe ọmọ PEARSE onile nla ti Eko, o ṣere diẹ nibẹ o si pada wa si ile lati wa palẹmọ nitori o ṣe nya ti o ma gbera, " B' egun ba ma lọ, a ṣa di iroju Atokun " a ti lọ ṣe bi ẹnipe ki o ma lọ mọ bẹ lo fẹ ri lara wa, A gbadun rẹ pupọ ju.

Nigbati o fi ma to nkan agogo mejila Ọkọ ṣi, o ṣe ya, gbogo awọn enia si sin titi ki nwọn to pada, Bayi ni *Lawyer Shyngle* " Baba n' ile, Baba l' oko" wa si Ondo ti o si kuro nibẹ pẹlu ayọ ati inudidun A ko le pari irohin yi laidupẹ ọpọlọpọ fun LADAPO ARINKUGBE ẹniti o fi Pẹtẹsi nla rẹ jinki ilu fun Alejo nla yi, ati ikẹ ati igẹ ti o fi fun, a si dupẹ lọwọ gbogbo Ijoye, ati awọn ara ilu ti nwọn ran Ọba lọwọ ni oniruru ọna lati tẹ alejo wa lọrun; o daniloju pe Loya papa bi a ba ieri yio sọ wipe on ko mọ pe ilu bi Ondo le ṣe ribiribi bẹ.

A dupẹ lọwọ Ọlọrun pe eyi ṣe oju wa, a si ba Ọba OṢEMAWE yọ lọpọlọpọ fun anfani nla yi. Ngo pari irohin mi pẹlu Orin ilu wa kan fun Ọba OṢEMAWE.

Aiye Ọba ma san o;
Fọn tọn bi ẹni ya 'ran jẹ
Ibọbọ jẹ, ibọbọ mu
Ibọbọ m' aṣọ yo san bora.

FANOKUN.

## PREACHERS FOR TO-MORROW.
### AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ANGLICAN.**

...ne—St. Paul's ( Breadfruit ) — Preacher.
...m. — Ven Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
...p.m. do. — do.
9 a.m.—St. John's Arọlọya — Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do. — do.
9 a.m —St. Peter's — Rev. J. A. Cole
do. Ebute Ero. — Rev. S. J. Gansallo

**WESLEYAN.**

10.30 a.m.—Tinubu — Rev. A. N. Cole
7 p.m. — „ S. A. Pearce
10.30 a.m.—Olowogbowo — „ E. E. Williams
7 p.m. — „ J. C. Cole
10.30 a.m.—Ereko — „ S. A. Pearce
7 p.m. — „ E. K. Ajai-Ajagbe
10.30 a.m.—Ọbun Eko — „ D. A. Beckley
7 p.m. — Bro. N. A. Thompson

**AFRICAN.**

9 a.m.—Jehovah Shalom — Rev. M. B. Newton
7 p.m. — Bro. Ignatius Martins
9 a.m.—Erelu — „ J. H. Lawson
4 p.m. — „ A. M. Williams
9 a.m.—Bethel — Rev. D. J. Oguntolu
6.30 p.m. — Rev. E. Akinọla
10.30 a.m.-African Methodist — Bro. O. Adefolu
4 p.m. — „ O. Ajayi

**BROTHERHOOD.**

7.30 a.m. — Bro. Arinọla Ibaru
7 p.m. — Prof. Adeoye Deniga

## LEGAL NOTICE.

In the Supreme Court of Nigeria.
In the matter of the Estate of
ISHMAEL IDOWU OGUNTOLU. (*Deceased.*)

Notice is hereby given that all creditors having or pretending to have any claims or demands against the estate of Ishmael Idowu Oguntolu late of 148, Strachan Street, Ebute Mẹta (Lagos.) Nigeria, deceased, who died on or about he, 12th day of April, 1922 intestate, at 148, Strachan Street, Ebute Mẹta (Lagos) aforesaid, and Letters of Administration of whose personal estate were granted by the Supreme Court of Nigeria to me the undersigned Elizabeth Oguntolu his widow of 148 Strachan Street, Ebute Mẹta, (Lagos) Nigeria on the 15th day of August, 1922, are hereby required to send in particulars of their claims and demands in writing to me the said undersigned at the above address on or before the 30th day of December, 1922.

And Notice is hereby given also that after that date, I will proceed to pay and distribute the assets of the said deceased among the parties entitled thereto, having regard only to the claims of which I shall then have had notice.

And all persons indebted to the said estate are required to make immediate payment of their indebtedness.

Dated the 29th day of August, 1922.

ELIZABETH OGUNTOLU
*Administratrix.*

## ILE OWO IFE OLODUMARE.

Ọgbẹni Onișowo M. Bankọle Fadipẹ mura tan lati ranșẹ orișirișị Ọja fun ẹnikẹni lati ilu-oyinbo.

Ibașẹ Ọja bi Ewe-taba, Ẹtu-ibọn, Awo, onjẹ-inipanu, Ẹrọ-ere ọmọde, Asọ, ati awọn nkan bawọnni,

Enia le san Idamẹrin tabi Idameji owo silẹ gẹgẹbi iye-owo ọja rẹ ti to.

Awọn oyinbo rẹ ni ilu Germany șetan lati gba enia lawin ọja; nwọn yio si fi ọja ti o ju idameji iye owo ọja ti o ba fi ranșẹ si wọn, șọwọ si ọ, a o si fun ọ laye Ọșu mẹta lati san owo toku. Mașini Ọlọwọ ati Ẹlẹșẹ daradara (Ọlọkọ rubutu ti Germany) nbẹ.

Ọgbẹni onișowo yi nfi Cocoa, Ekuro, Epo ati orișirișị Awọ Ẹran șọwọ si Ilu Oyinbo fun tita.

Ẹ lọ ba orire nyin pade lọdọ Ọgbẹni onișowo yi ni Ile-owo rẹ

Ebute Oluwa.
158, Marina L'Eko.

## Advertisements.

### IPOLOWO ỌJA.

### IJỌ GBOGBO ENIA DUDU,

### TI IWỌ ORUN AFRICA LABẸ GẸSI.

A nșe Ipade ti Ẹka Ẹgbẹ yi l' Eko ni ijọ ẹkẹrin ọsọsẹ Alaruba, (*Wednesday*,) ni Arapa Hall, Williams Street, ni agogo marun-abọ ni irọlẹ.

Gbogbo Enia lape sibẹ.

### AWỌN ẸGBẸ OYINBO ONIȘOWO TI A NPE NI E. H. STEIN ARA HAMBURG. NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn onișowo ti Ilẹ Enia Dudu, nwọn ma nranșẹ Ọja fun enikẹni to ba fẹ ibașẹ Ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ta o wa lagbegbe *England* ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ẹkuro ti a ba fi ranșẹ siwọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Kosi ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranșẹ si won lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi sowo lọri tabi ki o kọwe si Așọju won nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-ișẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Forlo-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kowe ni ede Gesi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn oyinbo onișowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg

### "OȘEWỌNI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Așẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orișirișị ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, losọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

### Banuso ma b'enia sọ!

A nta Iwe Oyinmọmọ yi ni C. M. S. Bookshop nibi, kọbọ mẹrin pere ni ọkọkan (4d.)

### Ile Ita Egbogi ti Macaulay

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orișirisi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran ti dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Așẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DANWO: Ogun rẹ jẹ bi idan.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.